# ETO ITANIJI NI KOKO







## Ipínlẹ Ogun







NATIONAL LIBRARY OF NIGERIA
RECEIVED O.L.A
DATE 22/9/88

# OGUN STATE NIGERIA




Published by The Ogun State Information Service and
Printed by The Ogun State Printing Corporation, Abeokuta 1598/1187/500




**COLONEL RAJI RASAKI,** fss, psc
*Military Governor of Ogun State*

# AWON IGBIMO AKOSO IPINLE OGUN



**DR ADEGBOYEGA OKUOLA KETIKU**
*Commissioner for Agriculture and Natural Resources*



**ARCH. CLEMENT MOFOLORUNSO SANYAOLU**
*Commissioner for Works and Transport*



**DR (MRS) FELICIA OSIFUNKE KUKU**
*Commissioner for Commerce and Industries*



**COLONEL RAJI RASAKI, fss, psc**
*Military Governor, Ogun State*



**MR TUNDE ADEDEJI IBIKUNLE**
*Commissioner for Special Duties*



**MR GEORGE OLUGBEMI ADEKUNTE**
*Commissioner for Education*



**MR TIMOTHY OSIYEMI**
*Commissioner of Police Ogun State*



**LT-COL AGUNBIADE LAWAL**
*Brigade Commander 31 Field Artillery Brigade Headquarters Nigerian Army, Alamala, Abeokuta*



**MR TEBUN FAGBEMI**
*Commissioner for Local Government and Community Development*



**DR OLASENI SHERIFF AKINTOLA-BELLO**
*Commissioner for Finance and Economic Planning*



**MR DAVID A. OSINIBI**
*Secretary to the Military Government and Head of Service*



**MR JIDE TAIWO**
*Commissioner for Lands and Housing*



**MR ANTHONY OLUSEGUN OLUTUNFESE**
*Attorney-General and Commissioner for Justice*



**MR TAIWO ALLIMI**
*Commissioner for Information Social Welfare, Youth, Sports and Culture*



**DR ONNUOLA A. ADEWUNMI**
*Commissioner for Health*

# ỌRỌ IṢIWAJU

Lati igbati orilẹede Naijiria ti gba ominira ni ọjọ kini, oṣu kẹwa ọdun 1960, ko si awọn eto to muna doko lati maa kọ awọn eniyan mọra ninu eto ilu ṣiṣe. Nidi eyi, a ko le mọ erongba awọn ijọba atẹyinwa fun awọn eniyan orilẹede wa.

Sugbọn lọjọ toni, a ti mọ eto ati erongba ijọba fun gbogbo wa. Nitorinaa ni Aarẹ Ibrahim Babangida ṣe ṣe ifilọlẹ eto itaniji fun ọrọ aje, idaduro fun ra ẹni ati idajọ ododo MAMSER lọjọ kẹdọgbọn, oṣu keje ọdun 1987.

Aarẹ Babangida sọ lọjọ naa bayi pe:

> "eto itaniji yi wa 'lati le jẹki awọn eniyan orilẹede yi maa gbe pẹlu itẹlọrun, irẹlẹ ọkan ati pẹlu ifẹ orilẹede Naijiria lọkan wọn".

Eto itaniji ti bẹrẹ ni ipinlẹ Ogun ni pẹrẹu pẹlu ifilọlẹ eto naa ti Gomina Raji Rasaki ṣe ni ọjọ bọ, ọjọ kẹrinlelogun, oṣu kẹsan ọdun 1987.

Eto iṣakoso ijọba ni ipinlẹ Ogun rọ mọ kiko awọn ara ilu sodi lati le ri atilẹyin wọn gba ni gbogbo igba.

Eyi lo jẹki awọn ara ilu fara mọ ijọba ninu gbogbo eto rẹ. Ohun pataki ni pe ki awọn ara ilu maa lọwọ si gbogbo awọn eto ati erongba ijọba.

Nitori eyi ni eto itaniji ti ipinlẹ Ogun ṣe ko awọn ara ilu-paapaa awọn ti n gbe ni igberiko mọra.

Iwe yi wa gẹgẹbi afikun si ifilọlẹ eto itaniji ni ipinlẹ Ogun. Ero wa ni wipe yoo le jẹki awọn eniyan tubọ ko ipa ti wọn ninu eto itaniji yi.

**TAIWO ALLIMI,**
ALABOJUTO FUN ETO IROYIN.

Oṣu Kẹwa Ọdun 1987.



**Alabojuto eto irohin Ogbeni Taiwo Allimi nigbati o nka oro ikinikuabo nibi ifilole naa.**

## ỌRỌ ALAKOSO FUN ETO IROYIN, OHUN AMULUDUN, ỌDỌ, ERE IDARAYA ATI AṢA IBILẸ, ỌGBENI TAIWO ALLIMI NIBI IFILỌLE ETO ITANIJI LORI AYIPADA ỌRỌ AJE, IGBẸKELE ARA ẸNI ATI IDAJỌ ODODO, ẸKUN TI IPINLẸ OGUN NI PAPA IṢERE TI AṢERO, ABẸOKUTA LOJỌ 'BO, ỌJỌ KẸRINLELOGUN, OṢU KẸSAN, ỌDUN 1987

MO KI,
GOMINA IPINLẸ OGUN,
OLUDARI ỌWỌ KỌKANLELỌGBỌN AWỌN OLOGUN,
IGBAKEJI ỌGA AGBA AWỌN ỌLỌPA PATA,
ỌGA AGBA AWỌN ỌLỌPA IPINLẸ OGUN,
ADAJỌ AGBA IPINLẸ OGUN,
AWỌN ALAKOSO IGBIMỌ IPINLẸ OGUN,
AWỌN ALAGA IJỌBA IBILẸ,
ALAGA IGBIMỌ LỌBALỌBA IPINLẸ OGUN,
ẸYIN ALAYE,
ỌBA ATI IJOYE,
SỌNMỌRI LỌKUNRIN ATI LOBINRIN,

Inu mi dun gidigidi lati ki yin ku abọ si ifilọlẹ eto yi loni.

2. Bi gbogbo wa se pejupẹsẹ si ibi loni lọkunrin, lobinrin, lọmọde ati lagba ti fihan gbangba pe awa ọlugbe ipinlẹ Ogun ti ṣetan lati gba eto tuntun ti an fi lọlẹ loni tọwọ tẹsẹ.

3. Ayẹyẹ toni yi ko fi aaye silẹ fun pe ẹnikan ju ẹnikan lọ nitoripe olowo, talaka ati bọrọkini ilu ni ọrọ naa kan. Yatọ si eyi, awọn aṣoju ẹgbẹ alanu, ajọ oṣiṣẹ, awọn iyalọja, awọn igbimọ idagbasoke ilu, awọn ọdọ, awọn akẹkọ ati



**Gomina Rasaki nfun Dokita Arabirin Osifunke Kuku alabojuto eto okowo ipinle Ogun ni ododo eye.**

awọn miran gbogbo ni wọn peju pesẹ sibi loni lati fi atilẹyin wọn han si eto tuntun ti ijọba Aarẹ Babangida gbe kalẹ eyi ti gomina wa, Ọgagun Raji Rasaki si nṣe akitiyan lati mu kẹṣẹ jari.

4. Gbogbo wa ni a mọ idi pataki ti a fi gbe eto naa kalẹ. Iriri atẹyinwa fi han pe awọn ilana ti ijọba ti o ti wa lode sẹyin n gbe kalẹ ko kẹsẹ jari nitoripe a ko fun awọn eniyan wa ni iwuri ti o tọna. Ijọba ti o wa lode bayi fẹ lati mu eyi kuro patapata, nitorinaa ni a se gbe eto itaniji yi dide.

5. Ilana wọnyi ni yoo se atọna fun bi ọjọ ọla orilẹede Naijiria yoo ṣe ri. Ọpọlọpọ anfani nlanla ni o rọ mọ eto naa eyi ti a ko le mẹnuba tan; sugbọn eto naa wa lati mu ki gbogbo ọmọ orilẹede yi ni ẹmi ifẹ si ilẹ Naijiria laisi iyasọtọ nipa ẹsin tabi ẹya.

6. Mo fẹ lati mẹnuba ipa pataki ti igbimọ ẹlẹni mẹrindinlọgbọn ti o se amọjuto eto tuntun yi ko lati le ri wipe ifilọlẹ toni kẹsẹjari lai si ikọse kankan.

7. Bi a ko ba gbagbe, lọjọ ẹti, ọjọ kọkanla oṣu kẹsan, ọdun 1987 ni a gbe igbimo naa dide ti o si ṣe aṣeyọri ti a fi le peju pesẹ sibi loni. Mo fẹ lati dupẹ lọwọ awọn ọmọ igbimọ naa fun iṣe ribiribi ti wọn se. Mo ni ireti wipe eto itaniji yi koni pin si ifilọlẹ rẹ ti a nṣe loni. A ṣetan lati muu kẹsẹjari ati pe a o rii daju pe eto naa fẹsẹmulẹ fun ilosiwaju orilẹede wa, fun ara wa ati fun awọn ti n bọ lẹyin wa.

8. Kọ yẹ ki n tẹnumọ pe gbogbo wa ni a o jẹ anfani tabua ninu eto itaniji ti a n se ifilọlẹ rẹ loni. Nitorinaa, o yẹ ki gbogbo wa lọkunrin, lobinrin, lọmọde ati lagba rii daju pe eto naa ko fọri sọnpọn.

9. Lẹkan si, mo ki yin pe ẹ ku abọ sibi ifilole eto itaniji ẹkun ti ipinlẹ Ogun.

10. Ẹ ṣe pupọ.





**Isola Folorunso, Oludari eto MAMSER ti eka Ipinle Ogun nigba ti o n gba ododo eye lowo Gomina Rasaki.**

## ỌRỌ ỌGBẸNI IṢỌLA FỌLỌRUNṢỌ OLUDARI ETO ITANIJI FUN IRAPADA ỌRỌ AJE IGBẸKẸLE ARA ẸNI ATI IDAJỌ ODODO ẸKUN TI IPINLẸ OGUN NIBI AYẸYẸ IFILỌLẸ ETO NAA NI PAPA AṢERO, ABẸOKUTA LỌJỌBỌ, ỌJỌ KẸRINLELOGUN, OṢU KẸSAN, ỌDUN 1987

MO KI,
GOMINA IPINLẸ OGUN,
OLUDARI ỌWỌ KỌKANLELỌGBỌN AWỌN ỌMỌ OGUN,
IGBAKEJI ỌGA AGBA AWỌN ỌLỌPA,
ỌGA AGBA AWỌN ỌLỌPA NI IPINLẸ OGUN,
ADAJỌ AGBA FUN IPINLẸ OGUN,
ẸYIN ALAKOSO IGBIMỌ IPINLẸ OGUN,.
ALAGA IJỌBA IBILẸ GBOGBO,
KABIYESI, ALAKE TI ILẸ ẸGBA,
ẸYIN ỌBA ALAYE ATI IJOYE,
ẸYIN SONMỌRI LỌKUNRIN ATI LOBINRIN,

Lakọkọ, mo fẹ dupẹ lọwọ Aarẹ orilẹede wa, Ọgagun Ibrahim Babangida fun fi fun mi ni anfani lati jẹ alaga fun eto itaniji ẹkun ti ipinlẹ Ogun. Bakanna, mo tun dupẹ lọwọ Gomina ijọba ati awọn eniyan ipinlẹ Ogun fun gbigba ti wọn gba mi tọwọtẹsẹ lati jọ ṣiṣẹ pọ fun ilọsiwaju ipinlẹ yi.

Ọjọ toni jẹ ọkan pataki fun ipinlẹ Ogun eyi ti a ṣẹṣẹ ṣe ayẹyẹ ọdun kẹwa ti a daa silẹ.

Ni ibẹrẹ ọdun yi ni ijọba apapọ ṣe ikede awọn igbesẹ mẹtadinlọgbọn lati da ijọba pada fun awọn oloṣelu. Ọkan pataki ninu awọn igbesẹ wọnyi ni ti eto itaniji ti a nṣe ifilọlẹ rẹ loni.



**Gomina Rasaki nfun asoju awon obinrin kan lati abule ni ododo eye.**

Bi a ba ronu jinlẹ gidigidi awọn ohun wọnni ti o ti ṣẹlẹ sẹhin si orilẹede yi, a o rii pe awọn nkan abami wa ti o n ti wa gbungbun ti o si nlepa ati pa orilẹede wa run.

O tito ọpọ ọdun 'sẹhin nigbati awọn ọmọ orileede yi ti ara nta si ọna ti ilẹ wa ngba lọ si iparun ti bẹrẹ sii ke gbajare pe ki a tete tọwọ ọmọ wa baṣọ, akoko naa wa to wayi ti a ko gbọdọ kọ eti ikun si igbe iru awọn eniyan bayi. Ipe lati ni ọna oṣelu titun ti o dalori otitọ ati ọna lati bẹrẹ igbesi aye titun lo wa yẹ ko gbode kan ni ilẹ wa nisisiyi. O si jẹ ohun idunnu wipe ọna ati ra orilẹede Naijiria pada ni o mu ki ijọba Ologun pinnu lati gbe eto itaniji dide ki a le lo gẹgẹbi ọkan ninu awọn opo fun eto oṣelu titun ti a fẹ dawọle ni ilẹ wa.

Eto yi nikan kọ ni ọna ipalẹmọ ijọba ologun fun ipadabọ ijọba alagbada, eto nlanla ni ti a gbe dide lati le mu wa ji giiri si iṣẹ wa gẹgẹbi ọmọ ilu rere ti o ti ṣetan lati sin orilẹ-ede rẹ fun ire gbogbo wa.

Eto itaniji yi jẹ ọna lati mu wa mọ riri ẹwa ati ogo ti o wa ninu awọn aṣa ilẹ wa, ati awọn ọna ti a le gba lati ri wipe ọrọ aje wa pada bọsipo, ọna lati le ni iṣẹ oojọ wa lọwọ lai ma duro pe ki ijọba maa ṣe gbogbo iranlọwọ fun wa, ju gbogbo rẹ lọ eto yi wa lati kọ wa wi pe iṣododo lawujọ wuyi pupọ, ti ododo ba wa larin ilu, gbogbo awọn ohun ti mo ti sọ siwaju ko ni soro lati ni. Nitorina mo rọ yin, ẹ jẹ ki gbogbo wa jẹjẹ, ki a pinnu lati akoko yi lọ lati wẹ ara wa mọ kuro ninu gbogbo awọn iwa eeri wọnni ti o ti nṣe akoba fun ilosiwaju ilu wa, ki a se ọkan wa giri lati mu ile wa di ile olokiki nipa ọrọ ati iṣe wa.

Bakanna eredi eto yi ni lati ṣe idasilẹ awọn eto abinibi wa lorisirisi ọna ti yio mu ki a le ma fi iṣe ọwọ wa, ikoraeni ni ijanu ati ṣiṣe iṣẹ laireti ohun-kohun bi owo-ẹhin ṣe ohun amuyangan lawujọ wa ati igbeleke orilẹ-ede wa.



Odomobinrin Temitope Alagbe nigbati o nka ewi nibi ifilole naa.

Lakotan, eredi eto itaniji lori irapada ọrọ aje, igbẹkele ara ẹni lẹnu iṣẹ ati iṣododo lawujọ ni ipinlẹ wa, ipinlẹ Ogun ni lati ta wa ji ninu awọn iwa idibajẹ bi inakuna ati afẹ aye ki a si bẹrẹ si ṣe ohun gbogbo ni iwọntunwọnsi.

Gẹgẹbi ọrọ olori ilẹ wa, Ọgagun agba Ibrahim Badamọsi Babangida, iṣọkan ati iṣododo ni nmu orilẹ-ede gberu si i lojojumọ.

Ẹ ṣe pupọ, ki Ọlọrun ki o bukun yin.



Gomina Rasaki n fi ododo eye si Akarigbo ti ile Remo, Oba Moses Awolesi laya.

## ỌRỌ GOMINA IPINLẸ OGUN ỌGAGUN RAJI RASAKI, NIBI AYẸYẸ IFILỌLẸ ETO IPOLONGO ITANIJI LORI AYIPADA ỌRỌ AJE, IGBẸKẸLE ARA ẸNI ATI ISODODO LAWUJỌ (MAMSER) ẸKUN TI IPINLẸ OGUN NI PAPA AṢERO, ABẸOKUTA LỌJỌ KẸRINDINLỌGBỌN, OṢU KẸSAN, ỌDUN 1987

MO KI,
OLUDARI ỌWỌ KỌKANLELOGUN AWON OLOGUN,
ỌGA AGBA AWỌN ỌLỌPA,
ADAJỌ AGBA IPINLẸ OGUN,
ẸYIN ALAKOSO IJỌBA IPINLẸ OGUN,
ALAGA IGBIMỌ LỌBALỌBA IPINLẸ OGUN,
KABIYESI, ALAKE ILẸ ẸGBA,
ẸYIN KABIYESI ATI IJOYE GBOGBO,
SỌNMỌRI LỌKUNRIN ATI LOBINRIN,

Ọjọ pataki ni ọjọ oni jẹ ni ipinlẹ Ogun nitoripe a n ṣe ifilọle ipolongo eto itaniji lori ayipada ọrọ aje, igbekẹle ara ẹni ati idajo ododo ni ibamu pẹlu ilana ijọba apapọ towa lode bayi ni papa Aṣero, Abẹokuta.

2. Ifilọlẹ toni yi jẹ ohun pataki nitoripe o jẹki ogunlọgọ awọn eniyan lọkunrin, lobinrin, lọmọde ati lagba lati ijọba ibilẹ mẹwẹwa peju pesẹ sibi lati fi atilẹyin wọn han si eto ti a n fi lọlẹ naa.

3. Mo fẹ mu wa si iranti pe lọjọ Abamẹta, ojo kedọgbọn, oṣu keje, ọdun 1987 ni Aarẹ Ibrahim Babangida ṣe ifililẹ eto itaniji naa ni Eko. Aarẹ Babangida ko deena pẹnu rara nigbati o sọ pato pe eto tuntun naa yoo ko ipa pataki ninu igbaradi orilẹede yi fun ijọba oloṣelu.



**Ogbeni Isola Folorunso, Oludari eto MAMSER, eka ti Ipinle Ogun n fi ododo ẹyẹ si Gomina Rasaki laya.**

4. Mo fẹ sọ pato pe eto toni yi ko ni pari sori gbigbe ijọba le awọn oloṣelu lọwọ lai si wahala kankan. Ẹto itaniji yi wa lati fopin si awọn iwa palapala bi aiṣotọ, ainitẹlọrun ati aigbaraẹnigbọ ti o ti gbilẹ lawujọ wa:

5. Ijọba ti o wa lode bayi ti ṣetan lati jẹki gbogbo ọmọ orilẹede Naijiria ji giri si bi a ṣe le maa ni ifẹ ara wa ki a si maa gbe igbesi aye rere.

6. Bi a ṣe ngbese lọ si igba tuntun, o yẹ lati maa gbero rere ti o le mu ki a ni ifọkanbalẹ lawujọ wa. O ti han gbangba pe eto itaniji ti a n filọle loni nikan ni o le jeki orilẹede Naijiria bọ ninu ojojo ti o nṣe ọrọ aje rẹ bayi.

6. Bi a ti n la kaka lati mu ọrọ aje wa fẹsẹmulẹ, a gbọdọ maa ri daju pe a dawọle awọn ohun ti o le mu wa di ẹniti yoo maa da se ohun gbogbo, ki a dẹkun iwa fayawọ, ki a ṣe ofin lati dẹkun awọn ti nsa fun owo ori ati lati maa pese ohun elo ni ilẹ wa nihin.

8. O ṣe pataki pupọ lati le da duro funra wa. Orilẹede ti o ba ni awọn ohun amuludun lorisirisi ni a le pe ni eyi ti o ti toju bọ. Awọn ohun amuludun bi oju ọna ti o dara, ile iwosan ti ohun elo pe sibẹ, awọn ile eko ti o muna doko, ina mọnamọna, iṣẹ ọgbin ti o see gbara le ati omi ẹrọ.

9. Awọn erongba eto naa ni wonyi.

(*a*) Sise eto ẹko wa lati jeki akọsẹ ọwọ wa fun awọn akẹkọ ilẹ ẹkọ girama. Eyi yoo le jẹki wọn da duro funra wọn lọjọ iwaju.

(*b*) Sise ise aṣekara lati le ri daju pe ise ọgbin fẹsẹmulẹ daradara. Iwuri yoo wa fun awọn agbe lati le jẹki wọn maa pese ounjẹ lọpọ yanturu, ki won si maa gba ere ise won ati ki won si mọ eto wọn pelu.

(*d*) Riri daju pe awọn eto ikọse ọwọ ti ijọba ipinlẹ Ogun gbe kalẹ kesẹjari.

(e) Mimu iwuri ba awon eniyan wa lati lọwọ ninu eto iran-ara-ẹni lowo.

(ẹ) Mimu iwuri ba awọn eniyan wa lati da ẹgbẹ alafọwosowopọ silẹ

(f) Iwa irẹlẹ dara lopọlopọ ati pe ẹda ti o ba ni suru ohun gbogbo lo ni.

(g) Ile iṣẹ ti o n moju to awọn ọja ti a n gbe jade ni ilẹ wa yoo maa ri daju pe wọn dara bi ti ile okere.

(gb) Mimu idagbasoke ba awọn igberiko lati le ri pe wiwọ wa si igboro ilu dopin.

10. Ọkan Pataki ninu eto itaniji yi ni idajọ ododo. Awọn ijọba latẹyinwa ni orileede wa ko sunmọ awọn eniyan ilu. Eto tuntun yi wa lati ri daju pe eyi wa sopin. Aṣiwaju gbogbo mọ ara rẹ si ẹniti o nse asoju awọn eniyan rẹ ti o si setan lati da won lohun fun ohunkohun.

11. Awọn ohun miran ti eto yi rọ mọ ni fifi opin si iwa ẹleyamẹya, aini anfani dọgbadọgba.

12. Mo fẹ sọ pato pe ipinlẹ Ogun ko ni kaarẹ rara lati ri daju pe eto itaniji yi kesẹjari. Ipinle Ogun tile ti bere eto naa tipẹ tipẹ.

13. Idaniloju wa pe eto naa ko ni fori ṣọnpọn. Inu mi dun pe awon baalẹ ati asiwaju ilu wa laarin wa loni nitoripe awọn gan ni yoo maa polongo eto naa ni ibugbe wọn lohun.

14. Ijọba Ipinlẹ Ogun ti ṣetan lati ri daju pe eto itaniji yi kẹsẹjari. Ẹbun ti a fun awọn ọmọ bibi ipinlẹ Ogun ti wọn se aṣeyọri ni ọdun 1986 ti fihan pe mimu iwuri ba awọn eniyan wa nikan lole jẹki wọn maa ṣe iṣẹ de oju ami. Ijọba yoo tubọ maa se eyi bakanna ni a o maa fun awọn agbẹ ati awọn miran ni ẹbun fun aṣeyọri wọn.

15. Nitori bi ọrọ aje wa ṣe wa loni, o ti di dandan ki a pada sori iṣẹ agbẹ mo ti n sọ tipẹ tipẹ pe ijọba yoo maa fi owo diẹ kun owo ti a n san lori riro ilẹ lati le din ẹru awọn agbẹ ku jọjọ. Bakanna ni ijọba yoo maa mu iwuri ba awon agbẹ lati da ẹgbẹ agbẹ alafọwọsowọpọ silẹ.

16. Mo fẹ lati mẹnuba pe bi ọrọ aje ba fẹsẹmulẹ ni a le da duro funra wa. Nidi eyi, ijọba yoo tubọ maa ṣe eto ti o le mu ọrọ aje wa dide lati le mu iwuri ba awọn ọdọ ki wọn le da duro funra wọn.

17. Lati le ri wipe awọn eniyan wa ri idajọ ododo gba ni ijọba se da ajọ eleti gbaroye silẹ ki o maa gbọ ẹdun ọkan wọn.

18. Mo fẹ mu da gbogbo wa loju pe, eto itaniji ti a nṣe ifilọlẹ rẹ loni ko ni fori sọnpọn. O ṣe pataki pe ki a rii daju pe eto naa kẹsẹjari lati le fi apẹrẹ rere lelẹ fun awọn ọmọ wa ti n bọ lẹyinwa ọla.

19. Lati le ri pe a n ba eto naa lọ, ijọba yoo gbe igbimọ oludamọran kan dide eyi ti aṣoju yoo wa lati igboro ile ati igberiko. Inu mi dun pe igbimọ ti o ṣe eto ifilọlẹ toni yi ṣe iṣẹ naa ni aṣeyọri.

20. Ẹyin sọnmọri lọkunrin ati lobinrin, bi mo ti n kesi gbogbo awa olugbe ipinlẹ Ogun pe ki a gbe eto itaniji yi larugẹ, inu mi dun lati se ifilọlẹ eto itaniji fun ayipada ọrọ aje, idaduro funra ẹni ati idajọ ododo lole.

21. E se pupọ.

# ỌRỌ LATI ẸNU KABIYESI, ỌBA MICHAEL FATỌNA ELEWO TI ILEWO NI IBI IFILỌLẸ ETO ATUNṢE ETO ỌRỌ AJE ILẸ WA, IGBẸKẸLE ARA ẸNI ATI IṢODODO LAWUJỌ TI A ṢE NI PAPA TI AṢERỌ NI ỌJỌ KẸRINLELOGUN, OṢU KẸSAN, ỌDUN 1987

Gomina Ipinlẹ Ogun, Ọgagun Raji Rasaki, ẹyin alaṣẹ ipinlẹ Ogun, Kabiyesi Alayeluwa Ọba Oyebade Lipede, Alake ti Abẹokuta ati gbogbo awọn Ọba Ipinlẹ Ogun, gbogbo ẹyin eniyan ni lọkunrin ati lobinrin.

Mo dupẹ lọwọ gomina lakoko yii tori pe o fun mi ni anfani lati ba yin sọrọ. Bo tilẹ jẹ pe akoko diẹ ni mo ni ni arọ yii, sugbọn nkan ti o dun ninu mi ni wipe wọn mu mi yẹ gẹgẹ bi ẹnikan pe ki n wa duro laarin yin lati wa ba yin sọrọ. Gbogbo wa ni a ri pe ọrọ aje wa ti fi ori sọpọn, ki ni o fa eyi? Ẹsẹ ni. Iwa ibajẹ, aiṣotọ, aiṣododo. Nibikibi ti a ba wa, ti wọn fun wa ni aye lati ṣe ọga ẹ o ri pe bi a o ba ṣe ootọ, a o ni ni ilọsiwaju.

Mo fẹ fun yin ni ẹsẹ bibeli lati lọ ka nigbati ẹ ba de ile, ẹsẹ na ni Deuteronomi ori kejilelọgbọn lati ẹsẹ kini titi de ekejila. E jẹ ki a fẹran ara wa, e je ka ran ara wa lọwọ, ki ni a le se ka le mu ọrọ aje wa pada. Ikinni, a mọ pe ko si isẹ nilu, mo tẹwọ ẹbẹ si ijoba ki wọn da iṣẹ silẹ, ẹni ti o wa iṣẹ ti ko ri, nigba to ba ya a ko ẹgbẹ kẹgbẹ, nitorina gbogbo ẹyin adigun 'jale, mo bẹ yin, mọ fi orukọ Ọlọrun bẹ yin ni owurọ yi, gbogbo iwa ti ko dara e je ka fi sile e je ka dawo iwa jibiti duro.

Awọn alasẹ wa ti ma jade nisinyi, laipe a o si bẹrẹ si dibo, ẹni ti a ba yan oun ni o ma wa ni bẹ. Nitorinna ẹni ti a ba mọ pe ko se olododo ẹ ma jẹ ka pe, ẹ ma jẹ ka mu, ẹ jẹ ka ṣe otitọ, ẹ jẹ ki a ṣe ododo, nitori kinni, nibẹ

ni iyi wa, ere ki a ma sare ko ọrọ jọ oun ni a nsa, ti a ba lọ si awọn ile iṣẹ gbogbo ẹ o ni ri ẹni da yin lohun, bi ẹ lọ si banki wọn ni da yin lohun lasiko, bẹ lọ si hospital bakanna ni, ẹ jẹ ki a mu iṣẹ wa gẹgẹbi iṣẹ, ẹ jẹ ki a mura ka doju kọ iṣẹ wa, ko le jẹ nkan ogo fun ilu wa, asiko diẹ ni mo ni gẹgẹbi mo ti sọ ri. Sugbọn, ẹ ma jẹ ki a gbagbe, ẹ jẹ ki a pa ofin Ọlọrun mọ, oun ni o le gbe wa leke.

Ẹ ṣeun.



**Iyaafin V. A. Popoola nigbati o nka oro re nibi ifilole naa.**

## ỌRỌ LATI ẸNU ARABINRIN OLOYE V. A. POPOỌLA NI IBI IFILỌLE ETO ATUNṢE ETO ỌRỌ AJE WA, IGBẸKẸLẸ ARA ẸNI ATI IṢODODO LAWUJỌ TI A ṢE NI PAPA TI AṢERO NI ỌJỌ KẸRINLELOGUN, OṢU KẸSAN, ỌDUN 1987

MO KI GOMINA WA ỌGAGUN RAJI RASAKI,

AWỌN ALAṢE GBOGBO,

KABIYESI ALAYELUWA, ALAKE TI ILẸ EGBA ATI AWON ỌBA TI O KU,

AWỌN IYALOJA ATI EYIN SONMORI LOKUNRIN ATI LOBINRIN.

A dupẹ lowọ Ọlọrun fun anfaani ti ijọba ologun fun wa lati maa sọ si eto ti wọn ṣe lati fi ijọba tuntun lọ ile. Gbogbo ọna ti wọn gbe gba wọn fi ye wa wipe awa fun ra wa la ma ṣe Ijọba ara wa. Nitori idi eyi a ni lati ni iwa ikora ẹni ni ijanu. Awọn iwa bi iwa ole, iwa inakunna, iwa ainifẹ, ati iwa aini iforiti, oju kokoro ti a ba mu iyẹn kuro, imọ ti ara ẹni nikan, mo ro pe ijọba ti o mbọ yi yio dara fun wa. Ki a de ṣe iranti wipe a ti ṣubu lẹkan, wọn ni ti ọmọde ba ṣubu, a wo iwaju bi agba ba ṣubu a wehin, ki orilẹ ede Nigeria ki a boju wẹyin, ki a wo ibi ti a ti ṣubu ni, jọsi, ka dẹ gbiyanju lati tun ibẹ ṣe. Nitorinaa ni ijọba ṣe fun wa ni aye lati ma sọrọ si eto ti wọnnṣe, ko ma jẹ wipe wọn gbe le wa lọwọ ni. Wọn fẹ ka sọ ohun ti a fẹ ki wọn ṣe, awon naa dẹ n sọ ohun ti wọn fẹ ṣe fun wa. Nitorinaa a n pe gbogbo awa eniyan, omowe ati awa ti a o mọ iwe, awa agbe, awa onise ọwọ, awa oloja, ki a gbiyanju ki a ṣe ohun ti o tọ, ki a ma tori owo dibo fun eniyan, ẹni ti o ba yẹ ti a ro wipe yoo tọju wa ti yoo ba wa gbe ọkọ Nigeria de ebute alaafia, oun ni ki a gbe ṣi bẹ. Ati ṣubu lọpọlọpọ ki Oluwa ki o jọwọ gbe wa dide, ọrọ aje wa to loo lẹ yi ma kunna lọ ja, ki a da ọwọ ina alaina duro, ka dẹ ni ifẹ ara ẹni. Nipa bayi a o ni ijoba titun ti yio rọ ọkunrin ati obinrin ati ọmode ati agba ni irọrun.

Oluwa yio fun wa ni alafia, ki a jọwọ ki a ranti pe awa ni a ma fi ọwọ ara wa ṣe ara wa, ibo, ọwọ ara wa ni a fi nṣe ara wa o, ẹni ti ò ba yẹ ti a mọ pe yoo ba wa gbẹ ọkọ yi de ebute, oun ni ki a pe si bẹ nigba ti o baya. Ni ẹkan si mo dupẹ lọwọ ijọba ologun ti o fun wa laye lati ma sọ ọkan wa nipa ijọba ti onbọ. Ki Oluwa dakun ran wọn lọwọ, Oluwa a ran awa naa lọwọ, ka ma gbagbe iwa anikan jọpọn ki Oluwa gba wa lọwọ ẹ, ki a ba le ni ijọba to da lehin wa ola.



Oloye Hubert Ogunde nigbati o nsoro nibi ifilole naa.

## ỌRỌ LATI ẸNU OLOYE HUBERT OGUNDE NIBI IFILỌLẸ ETO ITANIJI ỌRỌ AJE ILẸ WA, IGBẸKẸLẸ ARA ẸNI ATI IṢODODO LAWUJỌ TI A ṢE NI PAPA AṢERO, ABẸOKUTA NI ỌJỌ KẸRINLELOGUN, OṢU KẸSAN, ỌDUN 1987

Mo dupẹ lọwọ Gomina wa Ọgagun Raji Rasaki, ati gbogbo awọn alaṣẹ ijọba ologun, mo dupẹ bakanna mo tun ki Kabiyesi wa Alake Ilẹ Ẹgba ati gbogbo awọn Ọba Alaye ati gbogbo awọn ijoye ati gbogbo awa ta wa nihin.

Ọrọ mi ko pọ pupọ, owe kan wa, mi o ba owe yi lọwo awọn agba sugbọn mo n gbọ, wọn ni *fifẹju ko ni lilaju* eniyan laju silẹ iyen ki ṣe pe o ni ogbọn tabi pe oni oye, emi a wa fi temi kun wipe didi ju kọ ni sisun, eniyan le diju ko ma sun, eniyan le laju silẹ ko ti sun lọ.

Ara awọn ti wọn laju sile ti wọn ti sun lọ ni awa ọmọ Nigeria oju wa lasilẹ a n rira bayi sugbọn ati sun lọ. Oun ti o n ṣelẹ lẹgbẹ wa a ko mọ, lara awọn ti o ti sọrọ ṣaju wọn soro nipa inakuna, wọn sọrọ nipa aile ko ra wa ni ijanu, wọn ṣọrọ nipa iwa ibajẹ gbogbo wa lati mọ, njẹ gbogbo ohun to wa yi ko si ladugbo wa, ladugbo yin ẹ ri ọmọkunrin o n ṣiṣẹ labẹ ijọba ẹ mọ gbogbo owo ti o n gba losu, sugbọn o n se ohun ti o ju agbara rẹ lọ.

Laye igba awọn baba wa bi wọn ba ri iru eniyan bẹ, ki ile to mo oro a gbe oluwarẹ ni sugbọn nisisiyi ijọba o je ka se bẹ ẹ, bi a ba wo ijọba ologun bi ẹ ba ti gbọ ijọba ologun, emi naa ṣe diẹ nibẹ bi ọdun kan ni 1940 ninu ogun agbaye (1939 titi de 1945) bi ẹ ba gbọ ijọba ologun ibọn lẹn gbọ yẹn o, ko si ohun ti o wa nibẹ ju ibọn, sugbọn nigbati ijọba ologun ba de nisisiyi ti wọn ba jọwọ eto wa fun wa, ti wọn ba ni o wa to akoko ki a mọ eto wa, ki ataji, ki a ran arawa lọwọ, eyi ti kuro ni ijọba ologun o ti di ijọba tiwa ni yẹn. O wa yẹ ki

a gbọ gbogbo imọran ti wọn wi yi. Ki n wa fi ẹjọ ti emi ṣe alaye fun yin. Ti mo ti bẹrẹ ere yi o ti di ogoji ọdun o le merin, lati ogoji ọdun o le mẹrin yi i, iṣe ara mi ni mo nṣe, adaṣe si ni.

Sugbọn ati se yẹn o ya ọpọlọpọ lara, Mechanic ko fẹ sẹ mechanic mọ o wa ati gba contract ti o fi ma ri owo, owo inakuna, ti ẹ ba ri eni ti o n ṣiṣẹ labẹ ijọba, ti ẹ ba tun ri ẹni ti o ni oun se contract ti o di July ti o ko awọn ọmọ mẹfa si inu aeroplane, ti o jẹ ọdọdun ni wọn nlọ lo isinmi ni ilu oyinbo, ẹ ba mi bere lọwọ rẹ pe nibo lo ti ri owo yi. O di igba ti a ba le bẹrẹ si ma beere lọwọ ara wa nibo loti ri owo. Nisisiyi ẹ n sọrọ ibo, gbogbo awọn ti emi ri ni adugbo, ole kanna ni mo ṣi n ri o, mi o ti ri ẹni ti o fẹ jade gan an lati sin ilu yi, nitorina gbogbo yin ni mo nkesi lọsan yi pe ka tara wa ji, ki a ni ikoraẹni-nijanu, ki a ni ise ọwọ ara wa, oun ni mo ro pe oni agbẹkele ju, emi o mọ satide bi mo ba n ṣiṣẹ nitemi o, nigba miran mi o mọ ojo isinmi.

Nitorina, gbogbo ọmọ Nigeria ijọba n kesi wa kataji, ati awa ta laju silẹ ta ti sun ati awa ta diju ti a o sun, wọn n sọ fun wa pe ka taji ki a mọ ẹtọ wa, ki a mo ohun totọ si wa, ki a mọ ohun to yẹ ki a se, ki a ko ra wa nijanu, k a ma na inakunna, ki a fi iwa ibajẹ silẹ, ki a dẹ mo ohun ti ijọba nṣe.

Ẹ ṣe pupọ.